# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE. TE NI GBOGBO LAWA

No. 703 MONDAY MAY 25, 1964 (2D)


## Ọkunrin kan sọ iyawo rẹ di afọju

KANO:- Ni ọjọ ẹti ti nse ọjọ kejilelogun osu yi ni awọn ọlọpa mu ọdaran kan Elijah Apati ẹni Ọdun Mẹrindinlogun ti o gbe nọmba 490WF Gwagwra Quarters ninu awọn onisowo pataki ilu Kano wa si waju adajọ fun ẹsun iwa ika ati ipala-

Ọlọpa ti o ba ọdaran na sẹjọ se ala ye fun ile ẹjọ pe ọdaran ni ni ẹmọbirin ẹlẹyinjuegẹ kan ti se yoruba ni ọrẹ ẹni ọdun mẹrinlelogun ọmọbirin na si sọ fun pe oju kan yo on lẹnu ni dagbalda gba. Lẹsẹkẹsẹ ni odaran na ba lo se egtogi kan fun omobirin na osi busi ni oju titi ti omobirin na fi kuro ninu ile odo rẹ lọ Si ile won ni alẹ ojo na.

Sugbọn nigbati obirin na de ile won ti o si sun ni ọjọ keji ti o di de ko le fi oju mejeji r'ran mọ. Ni won ba gbe ọmo na lo si ile iwosan fun itọju sugbon oju na ti bajẹ nigbati won bi obirin na lere ohun ti o mu loju o se alaye fun wọn ni awon alase ile iwosan na ba fi oro na han olopa, Adajọ ko tilẹ gbọ ọrọ ẹyọ kan lanu ọdaran na o pasẹ pe ki won mu obirin na lo si ile itoju osi yẹ gbigọ ejo na si ojo miran lori iduro adota ponun (£50) Bi iwonṣe ba ti ẹjọ na si ẹ mon gbo ninu iwe irohin wa.

## Dokita Okpara Sọ Pe :

# AJAKU - AKATA NI IJA ETO IKANIA TI A BẸRẸ YI

"KAKA KI O RỌ FUN EWE AGBỌN, KA--KA--KA LO TUN NLE!"

ENUGUN:— Ni Ọjọ Aje ti iṣe Ọjọ kẹtalelogun Oṣu yi ni Dokita Michael Okpara, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakukọ (N. C N. C.) tun sọ fun ipade awọn Oniwe irohin pe, ipinnu ti Ijọba on ṣe lati pe Apapọ Ijọba Naijiria lẹjọ si tun duro gbọningbọnin.



Dọkita M. I. Okpara
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila—Orun

Dokita Okpara tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ fun ipade awọn oniwe irohin na pe, "Ija ti a bẹrẹ lori abayọri eto ikania yi, ajaku akata ni ao fi ija na ṣe koda boya ija na ni yio tun ajọṣepọ wa ninu ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba ka."

O tuu sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, Ijọba on yio ja ija na titi de opin ti awọn o si ri i wipe, "otitọ lo bori ọrọ na, irọ ko ni tẹle ododo lailai."

Dokita Okpara tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe "Bi enia ba sọ iye ti awọn ara Ipinlẹ Ariwa pe iye enia ti ngbe Ipinlẹ wọn fun odi, odi na yi mi ori rẹ nigba mẹta laiko le sọrọ."

Siwaju si i ninu ọrọ rẹ, Dọkita Okpara tun sọ pe, Gbogbo awọn ti ori won ba pe ti nwọn si nṣe ẹgbẹ Oṣelu ti ki iṣe nitori owo nikan, ṣugbọn nitori awọn ọmọ wa ti mbọ lẹhin-Ọla, ni nwọn o gba pe, ipinnu rere ni Ijọba on ṣe lati kọ abayọri eto ikania na, ti nwọn ko si gba."

Dọkita Okpara ni, on du pẹ lọwọ awọn enia agbegbe Yenagoa, ni agbegbe Kalaba ti nwọn nkan saare si Ijọba on lori ipinnu ti awọn ṣe lati pe Ijọba Apapọ l'ẹjọ.

Ṣugbọn O sọ fun awọn enia na ninu ibere wọn pe, on ko nigba pe ki awọn enia na ni Ipinlẹ wọn lọtọ, gẹgẹbi ibere wọn, nitoripe, ẹgbẹ on fẹ ki nwọn da gbogbo Ipinlẹ kekeke silẹ yika Orilẹ ede yi, ki isi iṣe ni Ipinlẹ kan ṣoṣo.

O tun se alaye pe, bi awọn ba fẹ da ipinlẹ miran silẹ, igba kanna ni awọ yio jijọ da awọn Ipinlẹ na silẹ, ki iṣe ni Ọkọọkan bi ibere awọn enia na.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, gbogbo awọn Minista ti nwọn lọ si idalẹ ni Apapọ Ijọba ti kọwe si pe ki nwọn maa bọ wale nitori ipade ti nwọn ṣe yi.

Dokita Elias, Minista Alamojuto eto iṣe ofin ati idajọ ti o wa ni Geneva ti sare wale ati oloye J. M. Johnson to wa si Amẹrika.

Ni deede agogo mẹfa irọlẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria sare wa si Eko lati ilu rẹ, Bauchi lati wa ṣe ipade pajawiri lori ohunti awọn enia lero pe o jẹmọ ẹjọ ti Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria pe Apapọ Ijọba.

Ṣugbọn nigbati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọkalẹ ninu ọkọ Ofurufu pataki kan, on pẹlu awọn Minista meji sọ fun awọn oniwẹ irohin pe, "Ni t'emi o, ọrọ abayọri eto ikania ti di ohun ti a ṣe, ti a si ti gbagbe rẹ patapata."

Ni deede agogo mẹfa irọlẹ ni ọkọ ofurufu na ti kunlẹ si Ikẹja, bi ọkọ na si gunlẹ ti Abkbakar jane ti Alhaji Muhammadu Ribadu Minista Alamojuto eto iṣẹ awọn ọmọ ogun ati Alhaji Zana Dipchairman Minista Iṣẹ owo ati Aje nsọkunlẹ bọ, ni Oloye Festus Okotiẹ Ẹbọh sọ pe "Ha ha nigba wo ni ẹyin kuro l'Eko ti ẹ ko mọ? awọn mejeji si dimọ ara wọn pẹlu ayọ.



Dọkita ELIAS
Minisita eto iṣẹ Ofin ati idajọ



Alhaji Abubakar
Alakoso Apapọ Ijọba

Diẹ ninu awọn Minista ti wọn wa ni Ikẹja ni irọlẹ ijẹta na ni Oloye Okotiẹ-Ẹbọh Minista Alamojuto eto inawo fun Apapọ Ijọba Ọlọla Moses Ọlaorewaju, Minista Alamojuto eto iṣẹ ọlọpanu ati ọlọpa ode fun Apapọ Ijọba ati awọn enia sarakisaraki gbogbo wọn si tẹle mọto Abubakar wa si Eko.

Ni deede agogo mẹsan alẹ ni awọn Minista ṣe ipade pajawiri kan ti o gba wọn to wakati mẹrin ki nwọn to pari ninu ile Alhaji Abubakar Tafawa Balewa.

Gbogbo awọn Oniwe irohin ti o lọ sibi ipade na, nwọn ko gba wọn laye lati wọle, ṣugbọn Onirohin wa fi ye wa pe, Minista mẹrinla lo wa sinu ipade na on si fi eti kọ Ọrọ diẹ ti wọn sọ.

Alhaji Abubakar ti tun pada lọ si ilu rẹ Bauchi ni irọlẹ ana lati lọ ma a lọ isimi Ọsẹ mẹfa ti o gba lọ.

# Ere Bọlu Ilẹ Gẹẹsi Yio han Ninu Ẹrọ

## Aworan Ti Ilẹ Naijiria

LỌNDỌNU:- Ere idije ti ere bọlu fun Ife k a n ni ilẹ Igẹẹsi larin awọn agba bọlu ti West Ham pẹlu Lancashire, Preston Nork End eyi ti awọn mejeji na si j'jọjẹ orogun fun ara wọn, fun ọdun yi ni wọn yio gba ni papa iṣire ti Wembley Stadium ni 'lu Lọndọnu ẹg nlọgọ awọn enia ni yio si lọ wo iran ere na awọn enia na yio to (100, 000).

Awọn adije na si jijọ gba meji meji wọ ile ara wọn.

Ni ojiji ni bọlu gba ẹnu ile ti awọn Prestor ti ẹni to wa ni iwaju fun awọn West Ham ọgbẹni Byce si gba bọlu na wọle.

Aworan ere idije ti ife na yio jade ninu ẹrọ aworan ti ilẹ Naijiria lati ọwọ awọn alakoso eto irohin ti Ijọba ilẹ Igẹẹsi ni aworan na yio fi wa.

Eleyi ti jẹ anfani fun awo ran ilu Eko lati wo aworan na ni (channel 10) ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin-dinlogun oṣu yi.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Gẹgẹbi Ọlọrun ti fuu ọ ni suru pupọ, o daju pe iwọ yio le ṣe suru bi ọrọ nla ba delẹ. Gbogbo ero ti o ro lọkan rẹ lo dara. Maṣe ba ẹnikan yan odi.

PISCES (Feb 19 - March 20) Iwọ yio binu nipa ohun kan ti o pẹ ti o si ṣoro, ṣe suru ki o gba pe amuwa Ọlọrun ni ki o si gba imọran ẹlomiran, ẹnikan ni yio la ọna fun ọ.

ARIES (Mar 21 – April 21) Ori rẹ dara irawọ rẹ sunwọn o yẹ ki o tun ara rẹ se, nigbati o ba balejo pade ṣugbọn o yẹ ki o mọ tani ẹmi ti o yẹ ki o gbẹkẹle.

TAURUS (April 22-May 20) Ogun awure ti o ṣe yio fa ọkọ ire wa ba ọ. Ṣugbọn ija ile ni ọjọrọ larin iwọ pẹlu awọn ẹbi rẹ, ohun ti o dara ni pe ki o lọ sun

GEMINI (May 21-June 21) Ṣe suru, ki o si gba kadara Ẹgbẹ ti o fẹ ṣe yio mu anfani pupọ wa ni faaji lọ si ode lọ wo awọn nkan tita ati rira anfa wa fun ọ nibẹ

CANCER (June 22-July 22) Ka mu ti ara ti o ndun ọ kuro, ọjọ ire ni oni yi jẹ fun ọ, iya fara yio ṣe idina pupọ, wadi rẹ ki o si wo bi gbogbo nkan ti nlọ si

LEO (July 23-Aug 22) Bi o ti jẹ wipe rudurudu ki fi bẹrẹ, gbogbo rẹ yio toro ginigini ni ọsan yi maṣe ba ẹni kan jiyan, ki o ma ba sọ wipe, iwọ ko wi bẹ.

VIRGO (Aug. 23-Sep. 22:- Lo agbara si ọna rere ṣugbọn ṣọra ki o maṣe wa mọto loni ma si ṣe ba wọn ṣe ere pa loni. Maṣe gbẹkẹle ajeji enia.

LIBRA (Sept. 23-Oct. 23) Akoko owurọ yio dara ṣugbọn ede koyede le tẹ silẹ ni akoko irọlẹ gbidanwo lati sun orun diẹ iwọ o rire kan gba.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ẹnikan yio wa ba ọ lẹnu iṣẹ, o yẹ ki o sun orun diẹ ko si tọju ara rẹ, lọ si bi ara o ... pẹ ọ si, awọn enia yio si gbadun rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Arẹ yio mu ọ bi o ba ṣiṣẹ pupọ, ba awọn to nfẹran rẹ ṣe faaji diẹ, ki o si fẹran awọn ti o nfẹrọ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Arẹ yio mu ọ loni lọwọ irọlẹ iwọ yio si ri ere pupọ nkan lo nfẹ amojuto rẹ fi ọkan balẹ ki o si ṣe suru.

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe gbeyawo
TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KOKO TO AFOJUBA
Dan a wo iṣẹ anṣoṣo ki o ri iyatọ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA
"DYNAMIREN" TỌNIKI
ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa a ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara awọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun ọ si ded adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lago

## Ẹgbẹ Imọlẹ - Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu karun (24/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Ba gbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALOLA
Akọwe Agba

# IWE SI OLOTU

## AWA Na Nfẹ Ẹkunwo Owo-oṣu

Ẹ dakun ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to jade lojojumọ lati ba awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣẹ ṣọtọ nitoripe nwọn ti gba awa ti a nṣiṣẹ labẹ enia Dudu, ko si ẹkunwo fun wa rara awa ni o si nṣe iṣẹ to pọ julọ

Mo bẹ ẹnyin aṣiwaju ẹgbẹ osiṣẹ bi Michael Imodu ati Adebọla pe, ki nwọn mase gbagbe wa awọn enia Dudu ko nfun wa ni aye isinmi lẹhin ti aba ti ṣe ọdun kan tan.

Owo oṣu wa ko nle rara, ko si igbega rara, eyiti o tilẹ buru nibẹ julọ ni pe, a ki gba owo oṣu wa lasiko, awọn ẹlomiran ninu enia Dudu ko san wo oṣu titi di bi ọjọ kẹsan si ekejila oṣu.

Ni ọjọ kan na ni gbogbo wa ti nra ọja si a ti nra aṣọ, bi a ba ya owo ti ada ipari oṣu bi ọṣu ba pari a ki ri owo san ao wa ma da ọjọ titi ti oju yio fi mọ ti wa

Mo bẹ nyin ẹ ran lọwọ bi Ọlọla Morgan ba ti gbe iwadi rẹ jade ẹ ma gbagbe wa o Olotu mo dupẹ aye ti o gba mi o ẹkun wo oṣn ko ni rekọja nyin o.

Nibiti aiye de loni yi ko ye ki a ma ka irohin nkan to ba ti el ṣeni ọjọ-mjẹọmẹjọ mo a nfẹ mo nka lojojumọ iwe Irohin Imole ni o sile mọ fun wa ni Irohin lojojumo Ejọwọ o ẹjẹki a ma ri iwe Irohin Imole ka o

Emi ni,
J. Atọlagbe,

AKURẸ.



Ọgbẹni Boral

Emi ni
Lati Arẹmu
MUSHIN

## AdO Ekiti Fẹ Ile wosan nla

Olotu inu yio dun ẹba le gbami ni aye latikesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe iranlọwọ yi fun wa iranlọwọ ti anfẹ lati ọdọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni ile iwosan ti yio tobi ju eyiti owa ni ilu wa Ado Ekiti ọpọlọpọ awọn enia lo nku sinu ile iwosan to wa nlẹ nipe ki iṣe gbogbo ohun ti wa ni ile iwosan nla miran lo wa ni ileẹiwosan ti ilu Ado-Ekiti ati pe ki a si tun dupẹ lọwọ awọn ijọ Aguda to fi idi ile iwosan le lẹsi ilu Ado Ekiti inu wa yio dun bi Ijọba Ipinlẹ ba le ṣe iranlọwọ fun wa lati le kọ ile iwoṣan titun miran lati le din ọpọlọpọ iku awọn ọmọde ni ilu na. Inu wa yio si dun bi Olotu Ijọba Ipinlẹ na ba le ṣe iranlọwọ eyi fun wa Mo dupẹ o Olotu ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ o Amin.

Emi ni
Kọlawọle Olupo
ADO EKIT

## Oju Ọna Yi Ko Dara

Ẹdakun ẹgba mi ol aye diẹ ninu Iwe nyin ti nkọwa ni ọgbọn ati oye ti o si tun ntumọ Yoruba yekeyeke fun wa lati ba Ijọba Ipinle Iwọ-Orun sọrọ lori oju ona lati Ibadan lọ si Iwo.

Bi enia ba rin oju ọna na ko ni mọ wipe ọda wa loju ọna na nitoripe niṣe ni ọkọ yio ma jasi koto jasi gegele ojẹ wipe bi Oluwarẹ ba ti sọ ninu mọto larin ọjọ mẹta ara yio ma ro enia.

Mo bẹ gbogbo ẹyin Ijọba Ibilẹ Ibadan ati Iwo pe, ki ejẹ ki aran awọn enin to ngbe agbegbe ilu mejeeji lọwọ nipa pe ki a tun oju ọna na ṣe ki ojo ti o de.

Oju ọna na ti bajẹ rekọja nitorina oju ọna yi ti bajẹ kọja eyiti alẹ fi silẹ di igba miran, ẹba wa tete moju to ọna na o. Awọn enia to wa ni agbegbe na, lọgan ni nwọn ma san owo na owo ori si apo Ijọba.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Olotu fun aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni,
Alli Lawal,

Iwọ.

## A nfẹ Irohin Imọlẹ ni Akurẹ

Olotu, inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ ti njade lojojumọ lati ba awọn alaṣẹ iwe Irohin Imọlẹ sọrọ nipa iwe Irohin na ti ko ntete tẹ wa lọwọ, awọn ti o ba lọ si Ibadan Oshogbo ati bẹẹbẹ lọ ni on mọ ni wọn lọwọ.

Awọn diẹ ti nwọn ba ko wa si Akurẹ lọgan ni o ntan, ti ọpọlọpọ ko si nri iwe na ka rara ẹlomiran yio wahala titi ki o le ba ri iwe Irohin Imọlẹ ra gbogbo rẹ pabo ni o nbọ si.

Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le ni asoju kan ni ilu Akurẹ ti yio jẹ a mọ ri iwe Irohin Imọlẹ ka lojojumo

Nitoripe awa na fẹ mọ ka irohin lojojumo bi awọn ti nka oyinbo ti nka ti wọn ako fẹ ki awọn kan ma tumọ irọ fun wa mọ


BERE EGBOGI PATAKI YI TI NWỌN NPE NI:—

# "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani ṣeṣe ṣe iwadi rẹ fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba 'TOBI' ju lati ma mu ki nwọn le fi jọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio ma a jẹ rara, bẹ sini ko lewu ni lilo fun enia rara, yala Ọkunrin tabi Obinrin.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupọju, kọ nṣe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ amodi ni o nko ba enia bi Lakuregbe, Aiko le gbera nilẹ bi o ba joko, Aiya lile kiki tabi jija nigbana, Aiko le mi kan lẹ daradara Ara wiwo, tabi wiwuwo, Emi mimi họ-họ orişirişi amọdi miran pẹlu.
Ṣa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ yio ri ayipada ati alafi ti yio desi. Bere ni Ṣọbu awọn Elegbogi Jamani ni igboro Ilu Eko

PILENAB MIXTURE,

Egbogi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi tibi aiko gbọnsẹ dede ba nyọ lẹnu bere rọ ni
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWOII




# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni P O R A L ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ ototu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile, Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yiori iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwẹ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Phone:- 2278 (Ọj, Lagos Nigeria
Palmchurch Street, Ita Faji)

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE MAY 25 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Ikẹja, Agege |
| ABEOKUTA — — — — | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN — — — — — | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJEBU — — — — — — | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imope |
| IJESHA — — — — — — | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| EGBADO — — — — — — | Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ IŞẸGUN MAY 26 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Oyingbo Ejinrin |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu. Wasinmi Owode |
| IBADAN — — — — — | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagb Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU — — — — — — | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| JẸSHA — — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile wlagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Su-Aa, Iboro |
| ẸGBADO — — — — — | |
| EKITI — — — — — — | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ'RU MAY 27 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA — — — — | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU — — — — — — | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe şara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA — — — — — | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaşẹ, Iperindo |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ MAY 28 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN — — — — | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| JẸSHA — — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | Igbogila Ijoun, Imasai Owode |
| EKITI — — — — — | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ẸTI MAY 29 FRIDAY

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja,Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA — — — — | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN — — — — — | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU — — — — — | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imodi |
| IJẸSHA — — — — — — | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO — — — — — | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ABAMẸTA MAY 30 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo. |
| ABẸOKUTA — — — — — | Ijoko, Berekodo, Aşu, Wasinmi Owode |
| IBADAN — — — ... — | Akeroro, Idọfin, Lagun Şagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU — — — — — — | Aiyepe, Shagamu, Itaoşu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA — — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO — — — — — | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI — — — — — | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ AIKU MAY 31 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA — — — — — | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹ Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU — — — — — — — | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA — — — — — — — | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. Aiyetoro, Ado-Oda. |
| ẸGBADO — — — — — — | |
| EKITI — — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ AJE JUNE 1 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN OJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagry |
| ABẸOKUTA — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN — — — — | Itoko, Şojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwo Omu Mamu |
| IJẸSHA — — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO — — — — | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI — — — — — | Oke—Aiyedun, Ikọle |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati ọwọ EJON'GBORO

### WARRI

Ile ẹjọ giga ti paşẹ pe ki awọn alaşẹ Ile ẹkọ Bomadi College lọ san pọnun meje o le irinwo (£407) fun Iyaafin Egoyibo Ikpekpen nitoripe nwọn d duro lẹnu işẹ laiko sọ fun un tẹlẹ pe ko si isẹ mọ

### KADUNA

Ijọba ti pe gbogbo awọn iyawo Şọja jọ pe ki nwọn gbe ọmọ wa si Bareke loju-kanna lati mọ obinrin ti o mọ ọmọ toju ju ninu gbo-gbo wọn. Ijọba yio si fun ẹniti ọmọ rẹ ba dara ju ni ẹbun nla.

### IBADAN

Ọdaran kan, Oseni Akan bi ti o ji ọmọbinrin kan gbe salọ ti ẹnikan duro fun ninu ile ẹjọ ni nwọn ko ri on ati oniduro rẹ mọ. Awọn ọlọ-pa nwa wọn.

### ILESHA

Idamu nla ba gbogbo enia nigbati awọn ọmọ me ji nbọ lati oko pẹlu baba wọn ti igi nla kan si wolu awọn ọmọ na mọlẹ, awọn ti gbe oku wọn lọ si ile iwosan.

### JAMANI

Awọn ọmọbinrin mẹrin ti awọn lọ ko işẹ onişegun lati ilu kongo ni nwọn ko ri awọn mẹrẹrin mọ, şugbọn awọn ọlọpa nşe iwadi ohun ti o şẹlẹ si wọn.

### NICOSIA

Awọn Şoja Ijọba Turky ti yinbọn pa ọmọ ogun kan ti işe li Ajọ Igbimọ Aynaiye ni opin ọsẹ ti o kọja yi

### YABA

Awọn Ọlọpa ti mu Ọkun-rin kan nitoripe nwọn ri ewurẹ marun ti Ọkunrin na nkọ lọ ti ko si le sọ ibiti o ti ri awọn ewurẹ na.

### EKO

Awọn Olọpa ti mu Ọda-ran kan Mosudi Adewale ti o ngbe 30, Ofin Road ati awọn enia marun miran pẹlu rẹ nitoripe nwọn nta tẹtẹ ninu Ọja Jankara.

### BURBAN

Ogoji enia ni o farapa nigbati awọn ọkọ rẹluwe meji forisọ ara wọn, şugbọn ko si ẹniti o sofo, emi, nwọn i ko gbogbo awọn enia na lọ si Ile-iwosan.

### FARANSE

Arun kan ti bẹ silẹ nisisiyi eyiti ngmu enia ati ẹranko, awọn Oyinbo ko ti ri Ogun ti o le wo arun na san ti o ba ti de si enia tabi ẹranko.

### MANILA

Gbogbo ilu gbojikan fun ariwo nigbati Ọkọ Ofurufu kan, jalulẹ ti enia mẹsan ku bamubamu, ni ẹ kinşọgo ti awọn to ku si fara gbọgbẹ

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 703 MONDAY, MAY 25, 1964 (2D)


## Adamọdi Ọlọpa Kan Wẹwọn Oṣu Mẹsan

KADUNA:- Kẹkẹ pamọ gbogbo enia lẹnu nigbati awọn ọlọpanu mu ọdaran adamọdi ọlọpa kan, Joseph Oguns. ẹni ogun ọdun ti awọn ọlọpa sọ pe, ko ni ibugbe kan pataki wa siwaju adajọ kotu Ijọba ibilẹ Kaduna fun ẹsun pe, o npe arare ni ọga ọlọpa, o si ngagbu awọn oni Takisi ati awọn enia lainidi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na sejọ se alaye fun Ile ejọ pe, ọdaran na lọ si ibudo ọkọ Reluwe Kaduna ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu ti o kọja, nigbati o mọ pe awọn ọlọpa ko ni wa si ibi iṣẹ nitori wipe ọjọ na jẹ ọjọ isimi.

Bi ọdaran na ti de Teṣan ọkọ Reluwe, ni o ba ngmu awọn awamọto Takisi, ti awọn nko awọn ero ti o sọkalẹ ninu ọkọ reluwe ti o si sọ fun wọn pe, Ọga ọlọpa kan ni on, on yio si mu wọn lọ si kotu, o lero pe, awọn enia yio fun on ni riba"

Ṣugbọn lojiji ni Ọlọpa kan de, ti o si ṣe akiyesi gbogbo ohunti ọdaran na nṣe ni o wa bi lere pe, Ọga Ọlọpa ti bo ni iwọ awe ! Ọdaran na ko le dahun mọ ni nwọn ba mu wa si Teṣan.

Nigbati ọdaran na rojọ, ti o si gba pe on jẹbi, ṣugbọn aiko ni iṣẹ lọwọ lo mu on ṣe bẹ, ni adajọ ba ni ki o lọ fi pọun mẹtalelọgbọn (£33) tanran si kotu tabi ki o lọ fi ẹwon oṣu mẹsan jura, Ọdaran gba pe ẹwọn ni on o lọ nitoripe on ko ni owo lọwọ.

# Babalawo Kan Gba Owo L'ọwọ Ole

IBADAN:— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa mu Ọdaran babalawo kan, Laniidi Babani, ẹni ọdun mẹrinlelogoji ti o ngbe agbegbe kan ti a npe ni Abẹbi, wa siwaju adajọ Agba ile ẹjọ kekere fun ẹsun ole jija ati jibiti.

Ogbẹni Ishọla Williams ti o ba Ọdaran na ṣejọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kini ọdun yi ni awọn mẹrin jijọ sunpọ ninu ile on ni Oke-Ado. Nigbati on si ji ni ọjọ keji, pọnun mọkanlelogoji (£41) ti o wa ninu apo on ki awọn to sun, nwọn ti ji owo na gbe lọ, gbogbo ile ati ode ni awọn enia na wa, a tun wo gbogbo apo ṣokoto ati ẹwu gbogbo wa, a ko ri owo yi.

O tun se alaye pe nigbati awọn wa owo na titi awọn ko si ri ni awọn mẹrin ti a jọn jijọ sun ninu ile na lọ Ogbẹni Ganiyu Ọlaniran sọ pe on mọ Bab lawo kan ti o jẹ wipe atamatase. bi awọn ba de ọdọ rẹ yio sọ ẹnito mu owo na fun awọn

O ni lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ba mura, ti awọn si lọ si ọdọ babalawo na ninu ile rẹ ni agbegbe Abẹbi ni Ibadan lati wadi ẹniti o mu owo na.

IBADAN LO MỌ

O ni nigbati awọn de ile babalawo na, ni o ba lọ gbe ọṣanyin kalẹ ti o si fi awọn bura fun Ọṣanyin pe awọn ko ni purọ otitọ ni awọn yio sọ, gbogbo awọn mẹrẹrin gba ọrọ na awọn si bura fun Ọṣanyin.

Lẹhin na ni o tun fun awọn ni egbogi kan, ti o sọ pe, yio fi ẹniti o ba gbe owo na han lojukanna ṣugbọn nigbati babalawo na mọ ẹniti o gbe owo na tan, o pe ọkan ninu awọn ti orukọ rẹ njẹ Joseph Ajiboye sinu ile, o si gbaa owo na (£41) lọwọ rẹ, pe ti o ba le ko owo na fun on, kiakia, on yio kọ ni ọna ti yio rin.

Lojukanna ni Ajiboye ba ko owo na fun un, o si kọ Ajiboye pe ki o lọ pe awọn mẹta yoku lẹjọ pe, a wọn ba oa ni Orukọ jẹ, on si fẹ gba owo itanran,, eyiti on yio fi tun Orukọ na ṣe lọwọ awọn

Nigbati o jade lọ ba ni ki awọn maa lọ ki gbogbo awọn si tun pada wa ṣugbọn Ajiboye gba Teṣan Ọlọpa lọ, o si lọ sọrọ na fun awọn Ọlọpa, lẹhin eyi ni Ọlọpa ba wa ko gbogbo awọn pe, awọn ba Orukọ Ajiboye jẹ pe, ole ni.

Adajọ ti yẹ gbigbo ẹjọna si ọjọ iwaju, bi awọn ba si ti pari ẹjọ na si, ẹ o tun maa a gbọ ninu iwe Irohin wa.


TRADITION REFLECTED IN PROGRESS

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor;- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 25/5/64